## Awọn aṣoju ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre yan sode lati dibo fun



J. F. ODUNJO
Egbado West



J. O. OPADINA
Ifẹ North



C. A. WILLIAMS
Ijẹbu East



K. Y. S. MOMOH
Afenmai East




# Owo ti wa a ri l'ori koko rẹ yio pọ si bi o ba ntu 'PERENOX' TABI 'PEREPOD' si i l'ara

# Ki arun ti mba Koko jẹ (korikori) ma ba ran an

Ninu awọn Garawa oni iwọn ẹsun mẹrinla (14 lb) ni "PERENOX" wa
tabi
Ninu awọn Garawa oni iwọn ẹsun meji (2 lb) ni "PEREPOD" wa

Pẹlu oṣuwọn ati iwe apejuwe kekere l'ọfẹ

Didi ni awọn Garawa ogun na wa lati ri i daju pe nwọn wa ni ẹkun rẹrẹ ati pe ko ma fi le bajẹ rara.

Kii pa enia ati awọn Ẹranko l'ara bi nwọn ba loo l'ọna t'nwọn ṣe apejuwe lilo rẹ

O wa kakiri ẹka ile iṣẹ ati lọdọ awọn aṣoju
THE COOPERATIVE SUPPLY ASSOCIATION
tabi
THE UNITED AFRICA CO. LTD

Plant Protection Ltd.


## Ipade Ijẹbupeju

*Lati oju ewe kini*

ko gbọdọ ya si ọdọ Okenla aladadi. Ko si ẹgbẹ kan lẹhin Okenla. Ko si alabaro kan fun Okenla. Kini rere ti iru aladadi bayi le ṣe fun ara wọn tabi fun ilu wọn? Ẹ maṣe dibo fun Okenla. ỌPẸ ni ki ẹ dibo fun.

Nigbati Oloye T. A. Odutola dide lati sọrọ ariwo ta. Ọgbẹni Ọja ṣe alaye wipe bi o ba jẹ wipe iṣẹ ni a o fi ṣe idajọ ẹgbẹ ko si ẹgbẹ ti o yẹ ki a dibo fun ju Ẹgbẹ Afẹnifẹre lọ. I ṣiro ohun ti ẹgbẹ yi ti ṣe fun ilẹ Ijẹbu ati fun gbogbo ilẹ Iwọ-Orun Naijiria. Eto ti ẹko ọfẹ ni ko ni iye lori ni tabi eto ti ẹgbogi ọfẹ tabi eto ti ina lẹntiriki tabi eto ọda yiyọsọno tabi eto ti Ijọba Ibilẹ tabi eto ominira fun wa bi orilẹ ede? Ọgbẹni Odutọla sọ wipe ọna ti gbogbo Ijẹbu fi le fi ami imore wọn han ni ki nwọn dibo fun ỌPẸ. Tiletile, tayatayа tọmọtọmọ tọkọtọkọtọ ni o yẹ ki nwọn fi dibo fun Ọpẹ. Ki a jinna si awọn opuro.

## Ẹ dibo f'Ọpẹ

## Ẹgbẹ Fadahunsi

*Lati oju ewe kẹfa*

awọn na lowo. Bi apere oruko ẹgbẹ Fadahunsi ko si larin awọn ti alakuko daruko. Ọgbẹni Akintola sọ pe bi Fadahunsi ti le jinna ohun si on sọ yi ki o jade wa si gbangba.

Oloye Akintola sọ wipe irọ ni awọn alakuko npa wipe ẹgbẹ yi nya awọn iyawo awọn OLOPE lowo. Larin ọdun 1954 ati 1956 ni awọn alakuko kọ mu ẹru ba a kosi obinrin ẹyọkan ni gbogbo Iwọ-Orun ti o bere wipe ki nwọn ya on lowo, kosi obinrin kan soso ti a ya lowo. Bi D. K. Olumofin ti npurọ ọrọ yi ba si sọ wipe bẹẹkọ ki o daruko obinrin kobinrin ti ẹgbẹ ti nya enia lowo yi ba ya lowo larin akoko yi. Bi ko ba le sọ oruko iru obinrinbẹ, ki Olumofin pa ẹnu rẹ mọ. Ẹniti ko ba ṣe pẹlẹ lori ọrọ irọ ati isọkuso yio fatakorin ofin.


## Ẹ dibo Fun Ọpẹ

Ẹ Ma a Ka Iwe Irohin Yoruba
Nibi agbogbo fun Irohin Aladun


Printed by the Amalgamated Press of Nigeria Ltd. 5/7 Apongbon Street, Lagos. Editor: S. M. [illegible], 6 Chapel Street, Lagos.